Egbe ki o maa ba gbogbo gigisẹ (ti omi o de) ninu ina, ẹ ṣe aluwala yin daadaa

Lati ọdọ Abdullah ọmọ Amru ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji o sọ pe: A ṣẹri pada pẹlu ojisẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - lati Makkah lọ si Madina titi ti a fi kan omi ni oju-ọna, awọn ikọ kan yara fun irun Asri, ti wọn si ṣe aluwala ni ẹni ti n kanju, ni a ba wa ba wọn ti awọn gigisẹ wọn han ti omi o si de ibẹ, ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa sọ pe: «Egbe ki o maa ba gbogbo gigisẹ (ti omi o de) ninu ina, ẹ ṣe aluwala yin daadaa».

[O ni alaafia] [Ohun ti wọ́n fi ẹnu kò lé lórí ni]

Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ṣe irin-ajo lati Makkah lọ si Madina ti awọn saabe rẹ si wa pẹlu rẹ, ni oju-ọna wọn wọ́n rí omi, ti apakan ninu awọn saabe sì yara ṣe aluwala fún irun Asri debi pe gbigbẹ awọn gigisẹ fun omi han si kedere, ni Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- wa sọ pe: Iya ati iparun ninu ina n bẹ fun gbogbo olùṣe aseeto nibi fifọ gigisẹ nibi aluwala, o si tun pa wọn lasẹ ki wọn maa ṣe aluwala ni pipe.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/66392